Mumini o gbọdọ maa korira muminah, ti o ba korira iwa kan lara rẹ, yio yọnu si omiran lara rẹ

Lati ọdọ Abu Hurayra - ki Ọlọhun yọnu si i - o sọ pe: Ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - sọ pe: «Mumini o gbọdọ maa korira muminah, ti o ba korira iwa kan lara rẹ, yio yọnu si omiran lara rẹ» tabi o sọ pe: «Yatọ si i».

[O ni alaafia] [Muslim gba a wa]

Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - kọ fun ọkọ ki o maa korira iyawo rẹ ni ikorira ti yio ti i debi ki o maa ṣe abosi rẹ ati ki o pa a ti ati ki o ma ya si i; nitori pe dajudaju ọmọniyan wọn da a mọ aipe ni, ti o ba wa korira iwa buruku kan ni ara rẹ, yio ri iwa miran ti o daa; nitori naa yio yọnu si èyí tí o daa ti o ṣe deede, ki o si ṣe suuru lori èyí tí ko daa ti ko yọnu si, èyí tí yio mu un ṣe suuru ti ko si nii korira rẹ ni ikorira ti yio gbe e lọ s'ibi kikọ ọ.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/3071